Chief Secretary to the Govt


# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead

Vol. VI. No. 297 SATURDAY, OCTOBER 20, 1928. 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.



## *White's Radical Gonkiller.*

:o:

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs**, and sold only by

Victor White, Esq., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

Price: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[ *Fun Atọsi lailai ati titun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, l o si njẹ ki o ri aye wu arun mi silẹ.


Adm/
H ... usisibin

# TO STOP YOUR ACHES & PAINS

*SIMPLY USE*




For more than 40 years Sloan's Liniment has been used throughout the World. It is kept handy in many thousands of homes to give quick, warming relief from the pains and aches of Rheumatism, Lumbago, Neuralgia, Sprains, Bruises and other severe pains. No need to rub Sloan's—it penetrates and kills the pain instantly.

*Sold by all Dealers.*

Wholesale:

FASSETT & JOHNSON, Ltd,
86, Clerkenwell Road,
London, England.

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILE NI OWO GBIGBA RE.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

PRINCE EṢUGBAYI ELEKO LODE ỌYỌ.

A gbọ pe Lọya kan lọ sọdọ Prince Eṣugbayi Eleko lẹnu ọsẹ tok( ja lati bere lọwọ rẹ pe ṣe ki on ma ba ṣe ẹjọ rẹ lọ, a ko mọ bi otitọ leyi tabi aturu.

KI LO TI RI O?

O ta si wa leti fẹnrẹn pe Adajọ Agba ke si ọkan ninu awọn Lọya ṣaṣawẹrẹ wa lati wa sọ idi rẹ fun Kotu ti Lọya na ko ni fi jẹ dida lọwọwọkọ lẹnu iṣẹ rẹ: Eyi ti jẹ o?

## DUNIYAN—LABARI.

[ LATI ỌWỌ KEKERE-AWO. ]

IKU MBẸ!

Anu gidigidi lo ṣe wa lati gbọ ti iku Ọgbẹni Joseph Adeliyi ti o nṣiṣẹ Ṣabu fun awọn oyinbo G. B. Ollivant & Co., ni Ṣabu ti nwọn nta nkan mere-mere ọṣọ-ara ni Ẹhingbẹti. Ẹniti o jalaisi ni ile rẹ Adam Street, Oke-popo, lọjọ Satide ijẹjọ.

Nwọn gbe oku rẹ lọ si Ṣọṣi awọn Aguda ni irọlẹ ọjọ na fun isin ikẹhin lati ibẹ lọ si Ikoyi nibi ti o gbe fi ilẹ bora; a ki Ọgbẹni Francis Adeniji ti o nṣiṣẹ ni Munisipa ati awọn arakunrin rẹ iyoku ati awọn arabinrin gbogbo pẹlu awọn obi rẹ, nwọn ku ajalu na, Oluwa ko fi mọ bẹ, ki ọ si tu nyin ninu, a si tọrọ fun oku papa ki Ọlọrun gbe si afẹfẹ rere o!

AJẸLẸ STREET.

Adugbo yi nibiti awọn moto gbe ndo si, o ṣe pagun-pagun, iba dara julo bi awọn "Town Council" ba le kun ibẹ tabi ki nwọn tẹ ni ipo ti yio yẹ fun wọn ati fun anfani rinrin awọn mọto na.

"SURU BABA IRETI."

Ọpọlọpọ enia lo mọ ohun ti o ndun awọn lọkan ni rere lati ri ti o si mbẹ Ọlọrun loju mejeji si, a fẹ ki a mọ wipe, ni iwọn igbati a ba mbẹ Ọlọrun, fun ohun ti olukuluku wa ba nfẹ lọdọ Rẹ pẹlu suru ati ọkan mimọ, bi o ti wu ki pẹ to dajudaju Ọlọrun yio dahun si ọro oluwarẹ—a dun ṣe bi ohun ti Ọlọrun fẹ, aṣoro ṣe bi ohun ti Ọlorun ko fẹ,—eyi o wu ka wi ti Ọlorun laṣẹ.

KI TO YI?

Ringbindin ti a ri agbara epo pupa ti o nṣun larin ọsẹ to kọja lo mu wa ṣe abere bayi—Ekiti bababa lo difa ọjọ kan fun Ọrunmila ti o ntu owo rẹ jọ lai wi fun Eṣu! ... ... to-to o!

IGI YI KO JONA 'RE A YẸ PA,
TỌHUN KO JONA 'RE A YẸ PA.

Bi ẹgbẹ kan ba wa ti nwọn ba ni awọn nṣe otitọ nitorina ni awọn ti ṣe da ẹgbẹ na sile, a si ti mọ wipe gbogbo ẹniti o ba mbẹ ninu ẹgbẹ ni yio jẹ olotọ, eyi kole jẹ bẹ arara, ẹlomiran le ba ki a ri mi tabi ale-awo wọ inu ẹgbẹ na, ẹlomiran si le ba aniyan ki on le ri anfani ẹgbẹ jẹ wọ ẹgbẹ, bẹni ẹwẹ, elomiran si le ba ero ki on le ma ṣe anfani fun gbogbo ẹgbẹ na wọ ẹgbẹ.

Awọn ọgbẹ Dẹmọ nwọn npe ara wọn ni ẹgbẹ ti o nfẹ rere ilu, ti o si nmura lati ma ran ilu lọwọ fun ohunkohun ti o ba jẹ mọ rere ilu, ti nwọn si ni lati ma teriba fun Ijọba ti ilu mbẹ ni abẹ wọn, gẹgẹ bi ọmọ ti ni lati tẹriba fun baba rẹ.

Ṣugbọn ọna mẹta ni a ti fi awojiji wo ẹgbẹ na pe o da si, awọn apakan li a ri wipe o duro giri fun rere ilu, awọn apakan le duro ni iduro ale-awo, bẹni awọn apakan le duro fun anfani ara wọn nikan, nigbati ẹgbẹ ba duro ni ipin mẹta bẹ dajudaju ẹnu ko le dọgba, ko si ọna ti mọnafiki ko fi ni wa ninu ẹgbẹ.

Kilo njẹ mọnafiki ni ti Yoruba: awọn elede meji tabi a gbọ ti eku wi fun ẹiyẹ lo njẹ bẹ, bẹ ibiti oni-mọnafiki ba wa kole roju tobẹ segesege lo ni lati ma lọ, wayi o, bi ko ba si awọn ti o jẹ ọlọgbọn fẹfe ninu Dẹmọ awọn ara wọn papa ko ko lati soju ẹgbẹ na de ilẹ lai sọ ti awọn ẹniti o tilẹ, mba ẹgbẹ na ṣe kokowa gbanran, irufẹ awọn ẹniti o nfi ọgbọn ati eto mu ọna ti ẹgbẹ yio gba ti yio fi ma lọ dede ni a le ma ṣe adura fun ki ajinde-ara ki o ma jẹ fun wọn, a si tun ntọrọ adura fun awọn ẹniti o le ma ṣe ọpa-oke ọpa-odo tabi agbọ ti eku wi fun ẹiyẹ ki Ọlọrun le rọ wọn

lọkan ki o le tete ye wọn pe ko si antani kan ninu iyẹn, ati pẹlu ọmoluwabı ma nduro si oju kan ni.

Şugbọn o yẹ fun awọn olotu ẹgbẹ yi papa wipe nwọn ni lati ma woye daradara ( oye ni agba nwo ) ni iwọn igbati nwon ba ti nfẹ enia lara ki wọn maşe kọbi ara si iwa ọdalẹ tabi iwa mọnafiki ti ẹlomiran le ma hu larin ẹgbẹ, nitotọ ẹgbẹ Dẹmọ ti duro bi ( oja Oyigbo ti ko mọ wipe ẹnikan ko wa, ) igba ti o ba yẹ nkan ni a nşe, ni iwọn igba ti a ko ba ti nwoye ẹsẹ ti ẹlomiran ngbe daradara lati ode ki o to wọ inu ẹgbẹ, lọna miran ẹwẹ bı a ko tilẹ ni kọdọyi ọkan si ẹlomiran ki ẹgbẹ to gba si inu ẹgbẹ, ti nwon si tun wa npada şe segesege, ẹgbẹ ni lati şe suru ki nwọn ma ba ohun ti nwọn nşe bọ, nwọn ni " ẹ ma jampata mọ iwa ni yio kilọ fun oni-wa."

( *Koi ti pari.* )

---

KINI EBUTE-AWO ŞE DI ỌTA IJỌBA,

(*The Nigerian Government.*)

Ko dede ti mo fi lo gbolohun ede ori iwe yi, nipe ninu gbogbo adugbo ti o wa ni Eko ( *Lagos* ) Ebute-awo lo dẹti ju gbogbo yoku lọ ti Ijọba ko nani ati nibikita lati tun şe adugbo Ebute-awo ( ko kere lawo ) ninu awọn adugbo Eko gẹgẹ bi a ti gbọ ninu Itan Eko *History of Lagos* şugbọn o jẹ adugbo ti awon oyinbo kole ri cocoa, kernels ati palm oil ra ni.

Şugbọn emi mọ dajudaju bi aşa Ijọba Gẹsi *Nigeria* n pe bi o şe pe awọn oyinbo ni wọn ngbe adugbo Ebute-awo ni, ati bo şe pe awon oyinbo onişowo ni wọn ngbe ibẹ ni tabi ti won şe owo ni bẹ pẹln ni, Ijọba a ti şe itọju to yẹ totọ sibẹ, gbogbo amujẹjẹ ati adagun omi bẹni Ijọba ma kun pẹlu okuta ati ọda, gbogbo Titi *Streets* bẹni wọn ma titẹ pẹlu okuta ati ọda, opo Electric yọnyọn ni yio wa ni gbogbo ikọrọ *corners* ati awọn opopo ti a wi wọnyi, nitori ki ole maja awọn oyinbo, ( ngbọ olori kura la nfi oku oko ndo ) A bẹ ẹnyin Ijọba Gẹsi *Nigeria* ko ranti pe Ọlọrun to da ẹnyin enia funfun lo da awa enia dudu ẹmi kanna la ni şugbọn iyatọ to wa larin ara wa ni dudu, şugbọn ju gbogbo rẹ lọ tani ni ebi iyẹn, ati pẹlu itiju nla ni eyi jẹ ọmọ onile sun ẹ şe bi ewurẹ ajoji sun lori bẹdi ni iyẹwu, eyi ma pọ ẹnyin aşoju wa ni Municipal Benjamin, Zizer ati Doherty, ẹnyin ko ri pe Ebute-awo fẹ titunşe lọpọlọpọ awọn nkan wọnyi jẹ ni ni iya pẹlu.—1. Electric Lights & 2. Gutters.

Nitori na ẹnyin Aşoju wa ni " Town Council " agba di ọwọ nyin o, ẹ ba awọn Ijọba sọrọ nipa adugbo Ebute-awo, ki a ma şe aroye lọ mọ titi awọn Gambari ma npa owe kan ni ede ilu wọn, nwọn ni, " Ganniyafiji " itumọ rẹ ni pe irohin ko to afojuba,—ki owe na jẹ ti nyin o. Nitorina ẹnyin Ij[illegible] ba ẹ rin adugbo Ebute-awo yi wo bi [illegible] ni mo pa.

AJUMOBI.

---

A solemn Requiem Mass for the repose of the soul of the late Joseph A. Adebiyi who died on Saturday, the 13th instant, will be sung in the Church of the Holy Cross, Oil Mill Street, on Thursday next the 25th instant, at 7-30 o'clock a.m.

---

IROHIN ILE-ẸKỌ IPẸRU.

Mo juba o ẹnyin alagba,

O ya mi lẹnu lati gbo wipe Ọgbẹni x lọ ba Teacher ni Ile-iwe ti x ni Ipẹru, wọn si jọja ni ile-iwe won laifagun lọ titi ẹjọ sun, Rev. x jọwọ mo fi itẹriba bẹ Ọba Alapẹru ki o jọwọ ba wa bẹ Mr. x ki o ye şe apọn ija nitori ija ni Mr. x fi fọ oju nigbati ogun eşu dide ni arin Ijọ x ti Ipẹru lẹhin igbati Rev. x ko 48 enia lọ si Işagamu pẹlu ọlọpa ti o fi ko wọn nigbati o ko won de Shagamu o ni ki wọn bẹbẹ awọn Ijọ kọ nwọn ni awọn ko ni bẹbẹ bẹni Rev. x tun fi ọ l ọ p a ko awọn Ijọ rẹ titi wa de Ikorodu ni ọdọ x o si ti wọn mọle, nigbana awọn Mr. x wọn si şiro 121 ẹşẹ si ọrun x ni ẹnikan şoşo eyi ya gbogbo enia lẹnu, nigbana ni Ọgbẹni x ọlọla ti Ogere so wipe awon Ẹgba ko 28 enia ninu awọn ara Işaşa lọ si ẹwọn ni Abẹokuta o ni x tun ko 48 enia lọ timọle ni Ikorodu, o ni bawo ni a tun şe wasu fun ẹgbọn awọn yẹn tabi aburo wọn pe ko wa gbagbọ.

A gbọ dajudaju pe ẹluku ati oro ni wọn fi le awọn Ọgbẹni ọlọla x ati Ọgbẹni ọlọla x ati Ọgbẹni ọlọla x ati Ọgbẹni ọlọla ati Ọgbẹni ọlọla x kuro ni ilu fun isin Igbagbọ Kristi awọn ti o ba Jesu rin yi nwọn ki ija, nwọn ki nsọ, nwọn gbọ ohun ti Jesu pa ni aşẹ. Awa gbọ ; şe ọkanjuwa ni ko jẹ fun awa, şe awa ti yapa, awa si ti şina kirikiri bi aguntan ti o nu,ọsọsẹ şa ni awa nri ka, ẹ jẹki imọlẹ nyin ki o molẹ ni iwaju gbogbo enia awa ko fẹ fi oju si yẹn rara.

Awọn ọlọla ti wọn ti fi ẹluku ati oro le lọ iyẹn nigbati oyinbo rọ agba si Ijẹbu-ode awọn ni wọn ranşẹ pe lati wa gba awọn silẹ nipa suru wọn; nwọn wa şe atunşe nipa bẹ nkọ ni gbogbo awọn ara Ipẹru fi kọ Şọşi *Church* x Ipẹru nitorina a bẹ ẹnyin Ijọ x x x ati Ọba Alapẹru ki ẹ jọwọ ba wa bẹ Ọgbẹni x suru ni Jesu sọ fun gbogbo wa wipe ka jọ ma şe.

## IROHIN AWỌN IJỌBA GẸSI, ALATUNṢE AMU ILU TORO AWỌN ỌLỌLAJULỌ.

Adupẹ pupọ ni ọwọ awọn Ijọba Gẹsi fun ile fifọ ti nwọn mba gbogbo enia dudu nfọ nisiyi o mu ki anfani wa ninu ile ni gbogbo ilẹ wa, ṣugbọn mo fi ọwọ ati itẹriba bẹ ẹnyin Ijọba Gẹsi ẹ jọwọ ẹ ba wa bẹ awọn onikọrọnti ; ni aseko ojo yi ; ki wọn jọwọ lati ma ba onile damọran a ti ma tọju ẹru rẹ si apakan ni ile rẹ nitori aseko ti a wa yi tabi bi bẹkọ ki wọn ma fun wọn ni tapolih lati ma fi bo ẹru wọn tabi ohun ini wọn nitori ojo nba wọn ni nkan jẹ, adanu pupọ ni iyẹn jẹ fun onile bẹni awa enia dudu a ko ni isaju ara wa rara

Mo ki nyin pupo gbogbo ẹnyin Ẹgbẹ Demo ni Eko, ẹku atunṣe, Ọlọrun Oluwa Olodumare yio tun ile gbogbo nyin ṣe, yio si fi ibukun rere fun gbogbo nyin ni ile ati ni ọna nyin gbogbo—amin.

Emi ni tiyin nitotọ,
J. A. O. SHOMADE.

---

Nipa irohin wa ọsọsẹ agbe ẹnu le ọrọ nipa ọda owo ati owo asi fihan ọpọlọpọ ninu irohin na gẹgẹ bi ọja ko ti ṣe ta ni lọloyi nitori pẹ ko si ẹniti oma ra yala ni ẹdin owo ni tabi ni awin ṣugbọn gbogbo rẹ pabo ni nipa bẹ ọpọlọpọ awọn ọmọ wa ni ko ri iṣẹ ṣe tojẹ wipe wọn ka iwe marun mẹfa boya nitori pe wọn ko ṣe idanwo ijọba ni iyẹn ni (Extrance Examination) sibẹ-sibẹ bo ba ri iwe ni ọwọ wọn, to ba ka wa ri wipe wọn sọ sinu rẹ wipe awọn ko kọ iṣẹ *Messenger* iyẹn ni iṣẹ iranṣẹ lati ṣe boya owo irufẹ iṣẹ bẹ ko ju ṣile mẹdogun tabi pọun kan ni oṣu lo, eyi fi nhan wa bi inira ti wa ni arin ilu yi, ọpọlopo obi ni ko ran omo lọ si ile-iwe giga nitori kini ni wọn ko ṣe ran ọmọ lọ, to ba bi wọn, wọn o ri ka, ko si owo iyẹn labori, wọn a san owo ile ti wọn haya, wọn a san owo omi, wọn a tun san owo Income Tax eyiti wọn bẹrẹ ni ọdun ni, sọfun mi nibo ni won ti ma ri owo lati ran ọmọ lo si ile iwe giga. Ti owo ba dide iyẹn le mu ayipada rere wa si arin ilu wa yi. Mo fẹ fun yin ni labari kan, on to ṣe gende to jẹ wipe ko si ohun to ma ji mọ to jẹ wipe Edu lo lọ ji ẹyin ko mọ wipe gudugbẹ ndun ni Eko isẹyin. Nipa ẹniti oji Edu yi mo ri ka ninu iwe irohin ojojumọ kan wipe gende kan ti orukọ rẹ njẹ Samuel Ẹkun wọn ragabu rẹ wa si iwaju Adajọ Kotu Ọlọpa ọgbẹni H. A. Young, K.C, wipe o ji apo Edu kan ti obinrin kan to njẹ Sadatu obinrin yi oni o jẹ onibara on, wipe ni ọjọ diẹ sẹhin on wa ba sọrọ nipa apo Edu kan o si sọ fun on wipe ki on pada wa lai pẹ, Adajọ ja ni koro wipe ki lo ṣe ti iwọ ko fi ru Edu na ni ọsan gangan afi oru, Ọdaran dahnn wipe oju ni o nti on lati ru ni ọsan gangan, on ko si ni owo alaru. Ọgbẹni Kester ni ọdaran yi ti wọ ẹwọn ri, Ọdaran ni bẹni on ti wọ ẹwọn ri nitoto. Adajọ ni ki ọrọ ma gun pọun kan tabi ẹwọn ijọ mẹrinla. Kini ko ba mu odidi gende lati ji apo Edu kan elo ni ko ba ta, a mọ wipe o ti wọ ẹwọn ri, ṣugbọn ohun ti mo fẹ fi han yin ni pe bi ọja ba gbera, ti owo nṣe riti nilu ki ṣe apo Edu ni ọkunrin yi ko ba ji. Oluwa ko jẹ ki igba yi yipada si rere ni ọdun ni.

Gbogbo enia nigboro Eko ni yo ri ka ninu iwe irohin Daily News ti ọjọ Satide ijọ kẹtala oṣu yi wipe awon omo tani wọnyi, oro yi lo jẹ ako, le nipa irohin kan ninu iwe Daily News ti 21/9/28 nipa awon ọmọ wa ti wọn wa ni ilu oyinbo Ẹkundayọ Akerele ati Adetokunboh Ademola nipa wipe wọn yaju si obinrin kan Mrs. Jean Sinclair ni agogo mẹwa abọ ni alẹ ọjọ na, ọrọ na wa si iwaju Adajọ ọgbẹni Hay Hackett nigbati won pari ẹjọ yi Adajọ ni ki wọn san pọun meji. Lẹhin na ni atun ri ka ninu Daily Times ti ọjọ Monday wipe wọn gbe ẹjọ na lọ siwaju Adajọ Agba wọn si pa ohun ti Adajọ Kotu Kekere rẹ wipe ko si alebu kan ni ara awọn ọmọ wa wọnyi. Ohun ti awa ma sọ nipe "Tani awọn ọmọ wa wonyi ma fi iwa yi jọ," agbọ pe niwaju Adajọ kekere Loya Ṣolankẹ lo ba wọn ṣe ẹjọ yi, ni Kotu nla Loya Oyinbo lo ṣe, ẹyin ọkawe ẹ ko ni ṣe alai mọ awọn ọmọ mejeji wọn yi, ekini jẹ ọmọ ọgbẹni David Evaristo Akerele ti Bangbose Street ni Eko, Ekeji jẹ ọmọ Ọba Ademọla Alake ti Abẹokuta ni idi iya rẹ, okun to mu iya rẹ wa si aiye okun kanna lo mu ọgbẹni wa Loya Adeyẹmo Alakija wa si aiye nigbana ni awa yio bere wipe tani ẹyin ma fi iwa alebu bayi jọ. Asi ba awọn ọmọ wa ati Obi wọn yọ fun ibọ ti wọn bo ninu ẹjọ won, eyi yio si jẹ kilọkilọ fun wọn wipe mẹlọ-mẹlọ lo ni aiye ni ode oni, lẹhin ẹjọ yi ni o ta si wa leti finrin wipe Tokunboh ti wa ti kọja lọ si Cambridge

Gbogbo ẹyin ọkawe inu Eko Akete lati igbati iwe irohin yi tiwa ni yio ranti ọkan ninu akowe iwe irohin ti o pe ara rẹ ni "Atari Ajanaku" gbogbo yin ni ẹ oniran ohun to kọ nipa Arede eyiti o pe ni "Atarede ata rede" ka gbọ ti Jesu re mo mọ o" gbogbo ẹniti ogbe arede on lo mọ ajaga ti on ki ọrun bọ, ọpọlọpọ ni arede tirẹ ṣe ni ore to jẹ wipe wọn nlọ dupẹ ni Ṣọṣi wipe odi iye ọdun bayi ti awọn ti gbe arede bi enia ba nwo irufẹ iyẹn arede awun oluwa rẹ lati gbe ọpọlọpọ ti arede won nṣe Jẹlẹnkẹ loni yi wọn ti de ilu oyinbo ibi ti wọn gbe aṣa yi wa ko to wa di ohun akunlẹ bọ, ko to wa di orișa ti gbogbo onigbagbọ nbọ bi orișa, lapa odọ tiwa nihin ti aba bere lọwọ awọn ti wọn nsun kun arede wipe ki lo ṣe to fẹ gbe arede ko ye wọn, won ko si mo esi ti wọn ma fi, fun oluwa rẹ, ọpọlọpọ nitori ati jẹ Sacramont ni aya tabi ọkọ nṣe gbe arede, ọpọlọpọ nipa ogun obinrin tabi ogun ọkọ lo nmu ọpọlọpọ ran ju mọ nkan oni kan ṣugbọn iṣubu arede lati ọdọ okunrin lo ma nsaba ti nṣubu wa, a ko so wipe obinrin miran ko ni lọwọ ṣugbọn awọn ẹniti ama sọ wipe

a le ma wo bi aşiwaju ọdọ wọn ni ẹru ti nma wọ wa nipa bẹ o jẹ ki arede yi ru euia lati ma mu tabi ko wu enia lori, opọlọpọ ko kọ ko ma ba panşaga rin, tabi ko gbe panşaga ni arede nitori on to ba wun ni apọ ni ọrọ ẹni ologun ẹru ku aşọ rẹ jẹ okan, bi ẹlomiran gbe ọmọ ilu onilu ni arede lojiji lo ma fi ẹyin iyawo na gbalẹ, eyi jẹ ki arede papa su enia lati mu, bo ri arede lode ma şe wipe dạnọsungbo ni wọn eyiti ko jẹ alarede, ko jẹ ki ọkọ alarede ri imu mi nipa bẹ ọran alarede di ọwọ adura. Ni ọjọ Satide mọ ti ka ninu iwe Eko Akete lati ọwọ "Oluşakin" wipe nijọ Tuesday ijọ kẹsan oşu yi niwaju Ọlọla Adajọ Agba, Ralph Molyneux Combe wipe iwe ẹbẹ lati ja ofin arede tabi fun aşẹ to ba to obinrin to fi iwe yi si Kotu ni Matilda Ọmọpe Ọbafẹmi aya Ọgbẹni Charles Harrison Ọbafẹmi Loya ti Eko nibi. Loya Ọbafẹmi ko wa ta ọjọ ẹjọ yi ofi gbogbo nkan silẹ fun Kotu. Aya rẹ yi gba Lọya S. Ayọdele Thomas, obinrin yi ni on pẹlu ọkọ on gbeyawo ni Eko ni ọjọ kọkandilọgbọn oşu April 1919 ni şọşi alagogo Christ Church ni Eko, ati pe o da apa si ọrun ọwọ on osi, ati pe nigba kan oni lati le on jade kuro ni ile fun ọdidi oşu mẹfa ni asiko na on ni lati ma gbe ọdọ ọgbẹni Mends Cole ati pe ọkọ on nba obinrin kan ti oruko rẹ njẹ Ellen Eyinle Ọlaside gbe pọ ni ile kanna, nipari ẹjọ yi Adajọ Agba ni on ni itẹlorun si ẹri ti wọn gbe wa siwaju on. Adajọ fi aşẹ si pẹlu owo irin ẹsẹ fun aya. Decree Nisi with costs against the Respondent.

Gbogbo ẹyin awa Motor ni Eko, ẹsọ ko to yin nipa ọran ẹnu işẹ yin, ohun to mu mi lati şe kilokilọ yi fun yin, ohun ni nipa aigbọran, aibikita yin fun awọn Ọlọpa Ọba, bi wọn kilọ fun yin tinu yin ni ẹma şe, bo ti di ọran ẹjọ, ẹ ko wa ba oni Motor ko jowọ ko gba yin, nkan ba wọnyi ojẹ abuku pupọ, mo tun fẹ gbe ẹnu le ọran ẹyin awa Motor ni ọna oko, nitoripe ko si ẹniti owo wa ni ọwọ rẹ to jẹ ko lori Reo, Brockway, Chevrolet, Indiana, Bethelehem, Dodge tabi awọn Lorry alagbara miran nitori ati şişẹ ni ọna oko, ko si nşe gbogbo enia lo ma ma ba Lorry kiri ninu igbẹ bi Kọrah, ki şe wipe ko dara şugbọn ẹlomiran wa ni ẹnu işẹ rẹ, to jẹ wipe o nfi Lorry yi gbọ ọna miran. to si gbe le iwọ Driver lọwọ nikan, şugbọn to fi Sadu silẹ ni oke Ebute mẹtta tan to jẹ wipe ko si ẹniti oto ẹ mọ, eyi wa dara, ko wa di oşu meji Lorry tuntun ntitun awa di garawa, lẹhin na iwọ Driver a ma fi oju sode fun tuntun, iwọ awa Motor iwọ fi ọran yi we wipe bo ba şe iya rẹ tabi Baba rẹ ni iwọ ha le şe bẹ emi sọ eyi fun itiju yin, ẹ tun gba ọkan si awon oyinbo Reluwe wọn din owo ọkọ Abẹokuta ati Ibadan ni sẹyin, o dara pupọ nitori pe ofi enia ni okan balẹ wipe ko si ẹwu ninu rẹ aya fi awọn to ma nyọ iofofo kiri ninu ọkọ, lẹhin na irọrun wa ninu rẹ de ibi ti oba gbe nlọ ju ti Lorry lọ, ngbọ iwọ oni Motor ẹru ko ti pa Taya rẹ, nişe kọ ni Lorry ma ma ju sọtun ju sosi titi ọna fi gbe awọn ero de ibi ti o gbe nlẹ, inu furu ẹdọ furu kọ ni awon ero yio wa de ọhun, a kọ sọ wipe Motor ko yara ju Reluwe lọ, a ko sọ wipe Pleasure Car ko gbadun ju Reluwe lọ, şugbọn aya tani o nfo gbogbo enia, bi ko şe aya awa Motor mo le şe aya gbangba nipa Motor mi, o da bẹ şugbọn mo fẹ sọtun ẹ, wipe kọ si ẹniti ofin ko le lo yala o jẹ dudu ni tabi funfun, ọpọlọpọ awọn alai mọkan tabi awon amulọdọ won a ma rope bi adajọ ti şe bu owo sisan fun awọn awa Motor enia dudu, ko jẹ bu fun awọn oyinbo bẹ, emi fẹ sọ fun ọ loni wipe ita funfun ni eyi ti owi yẹn, ko ri bẹ rara mo ka ninu iwe irohin ojojumọ ti ọsẹ yi, wipe oyinbo wa Motor rẹ sere ju eyiti ofin fẹ lọ, awọn ọlọpa mu, wọn mu ẹjọ rẹ wa, siwaju Adajọ Kotu Ọlọpa ọgbẹni H. A. Young, K.C, ni ọjọ Monday ijọ kẹdogun oşu yi ni wọn mu oyinbo yi ti orukọ rẹ njẹ F. W. Priest olotu işẹ Wright & Co, ni ile ọlọgbe Disu Ige leti ti oyinbo awọn Ọlọkọ Elder Dempster & Co, ni Eko, wipe o nwa Motor rẹ ni ai bikita pẹlu imẹlẹ. Awọn ọlọpa pe ẹlẹri meji, wọn si sọ pe o nwa Motor yi sare to iwọn busọ marundinlogoji fun wakati kan, 35 miles per hour lẹhin na kosi bikita fun aşẹ Ọlọpa to nnọ ọwọ si wipe ko duro, oyinbo yi gba Lọya D. Hagley osi sọ wipe nkan ti Ọlọpa wi yi o purọ ni ati wipe on ko ri owọ Ọlọpa. Adajọ ni on ni itẹlorun si ohun ti awọn Ọlọpa wi ati ẹri ti wọn fi siwaju on, nitori na Adajọ ni ki oyinbo yi ko san ogun poun (£20) tabi ẹwọn oşu kan. Eyi le fi han yin, ẹyin enia wa, wipe ko si ẹniti ofin ko le lu, yala o şe dudu ni tabi funfun, ko ha yẹ ki ẹnyin a wa Motor ki ẹ mọ iwọn ara nyin, nitoripe oyinbo ko wa motor ẹlẹru, bẹni ko si wa gbọnkankan, şugbọn motor ara rẹ lo wa, oyinbo yi papa yio fi eyi kọ ọgbọn wipe ẹniti o ba fi oju di ọba awowo-awo.

Gbogbo ilu ni yio gbọ ẹjọ ti Ijọba nba awọn oyinbo Kọrah ro wipe gẹgẹ bi ofin Bode o ni iye iwọn aşọ ti wọn ni lati ka ninu irin şugbọn awọn Korah ko tẹle ofin yi. Awọn ọgbẹni wọnyi ni Ijọba nba ro ẹjọ, Nehemi Saidi ati Wadi, Mafud ni ọjọ Monday ni Adajọ Kotu Ọlọpa ọgbẹni H. A. Young fi opin si ọrọ na wipe nkan ti on ni lati ro wo nipe bi iye iwọn ti wọn ni lati ka sinu ọpa kan ni won ka tabi ohun kọ şugbọn lẹhin ti mo ro gbogbo ẹri ti wọn fi siwaju mi tan emi ri wipe kika ti wọn ka wọn ko tẹle ofin nitori na ko si ohun meji ti ohun ni lati se ni lati paşẹ wipe ki Ijọba ko gbe ẹsẹ le gbogbo ẹru na ati pe ki Gomina ko gba ni imọran lati pa ni aşẹ wipe ki wọn da gbogbo ẹru yi pada si ilu oyinbo ki won si tun ka. Adajọ si tun sọ pe ko si ni ero awọn ọgbẹni wọnyi lati şe ẹru fun Ijọba nitori na on ko le ba wọn wi tabi palaşẹ wipe ki wọn san nkankan Nitori na aki awọn ẹni wọnyi wọn ku ori re, asi ki awọn ẹni bi ọlhadji Kamil Lamidi Saidi wọn ku orire awọn ẹni wonyi. Ẹ yin enia wa,

gbogbo nkan nlọ pẹlu ofin njẹ ẹ̀in mọ wipe ofin wa nipa kika tabi bibun aṣ , ẹfi eyi si ọwọ osi nitori ọrọ ọlọrọ ni ari kọ gbọn.

Emi ni ti nyin nitotọ,

ENIA KO DA BI ALLAH.

ORI IV.

IṢẸ.

(*Translated from "Character by Dr. Smiles"*).

APA KOKANDILOGUN.

Ninu awọn oniwe ti o jẹ Olotu ile-owo (*Bank*) a ri Rogers ọkọwe orin; Roscoe ti *Liverpool*, ti o kọ iwe itan Lorenzo de Nedici; Ricardo ti o ṣe iwe *Political Economy and Taxation*; Grote ti o ṣe iwe *History of Greece*; Sir John Lubbock ti o nwadi awọn nkan atijọ ati Samuel Bailey ti *Sheffield* ti o ṣe iwe, *Essays on the Formation & Publication of Opinions* lai ka awọn iwe pataki miran nipa iwa, agbeka ero ti a fi nṣe ilu, ati nipa ọgbọn, eyiti o ṣe.

Bẹ si ni a ri i pe awọn Ọlọgbọn ati awọn ọmọwe san, ti fihan pe oniṣẹ pa ni wọn. Ẹkọ ti o dara ju ni eyiti o kọ ni bi a ti ṣiṣẹ, ti mu ni ro ero, ti fun ni lọgbọn, ti si fun ni ni Okun lati ṣe iṣẹ—gbogbo awọn eyiti oṣiṣẹ enia ko le ṣai ni.

Nitorina ni a ṣe ri i, niti awọn Ọdọmọkunrin, pe, ẹkọ-iwe a mu ti iwa dani; nitoripe eyi a fi ikunrinmọ, iṣẹ ati ẹkọ on itara ti a fi ikọgbọn han, a o si ri i pe iru awọn eni bẹ, a ja fif , ọrọ a da si wọn lẹnu, nwọn a ni ọgbọn, nwọn a si mọ nkan ṣe ju ọpọlọpọ enia lọ.

Montaigne ti sọ nipa awọn ọlọgbọn enia pe, "ti nwọn ba jẹ eni nla lọna Oye ti nwọn ni, ko si ootọ ni nwọn jẹ ninu iṣẹ-ṣiṣe,......nigbakugba ti a ba si fi aye silẹ fun wọn, a ri i pe nwọn a ṣe ohun ribiribi ti a fi dabi enipe ko si ẹniti o mọ to wọn.

Sibẹ, a ni lati gba pe ki a mọ ohun miran ju ti ki a nurimọ iwe ere ati iwe ero lọ, papa ti eyi ba ti di ara, ti a ko si le fi silẹ mọ, jẹ eyiti o nṣe ọṣẹ ju ti ki mu enia ya ọlẹ.

Ki a le joko ro ero bi a o ti ṣe nkan ati ki a le dide ṣe nkan na, ọna ọtọtọ ni; enia ti a ba si ri pe, bi nipa iwe kika tabi kikọ ni, o ni oye tabi ero ọna ti o to ki a gba ṣe nkan, bi o ba di oju ọgbagada tan le ma to lẹnu nkan na.

Ki a le joko ro ero nfẹ ẹniti o le rori de ka-nge—Ki a le dide ṣe nkan nfẹ ẹniti o le ṣiṣẹ de kanpe; enia kan ki isi ni mejeji dọgba. Enia ti o le joko ro ero ki isaba mọ ewo ni on yio mu ṣe: bi o nro lọ lọna yi, a tun ro lọ lọna miran, a si pa eyiti o fẹ ṣe ti na nibiti o gbe nro bi eyi lọna, bi tọhun ni, nigbapupọ ni ki isi ri ojutu rẹ; Ṣugbọn enia ti idide ṣe nkan ti kọja apilẹ ro ero, ọkan rẹ a mu ọkan ṣe a si yara bẹrẹ si iṣẹ ṣe.

*Translated by*

ADEYINKA AJAGBE-ỌSA

## OFIN IFẸ MẸWA FUN AWỌN OBINRIN WA.

1. Iwo ko gbọdọ ni ọkọ miran lẹhin emi nikan. Mr. Fine.
2. Iwọ ko gbọdọ wọ aṣọ alarabara ti Mr. Dandy wọ.
3. Iwọ ko gbọdọ ṣe oju kokoro lati mu ọkọ rẹ nipa ṣe ohun ti agbara rẹ ko to.
4. Iwọ ko gbọdọ ra ọja awin, yala ni golu tabi aṣọ to dara.
5. Iwọ ko gbọdọ gbe oju gangan si ọkọ rẹ nile, tabi lati ma ko ẹgbẹ kiri lode.
6. Iwọ ko gbọdọ ko gbogbo owo ọbẹ ọkọ rẹ lati fi ran ohun ọṣọ sara.
7. Iwọ ko gbọdọ ṣe igberaga si ọkọ rẹ. Ranti wipe on ni o wa ọna atijẹ ati atimu rẹ.
8. Iwọ ko gbọdọ ṣe ojukokoro si ọkọ ọrẹ rẹ bẹni iwọ ko gbọd ọkọrira awọn ẹbi ọkọ rẹ, yala kekere tabi agba.
9. Iwọ ko gbọdọ tu aṣiri ọkọ rẹ si ita, nitori wipe o yẹ ki itẹlọrun wa lori tọrọ tabi sisi ti o nfun ọ lati fi gbọ onjẹ ojọ rẹ.
10. Bẹni iwọ kọ gbodọ gbe ori rẹ ga si ohun kohun ti mo le sọ fun ọ nitoripe emi ni ọkọ rẹ, fi mo si ni agbara lori rẹ gẹgẹ bi Adamn ti ni agbara lori Efa aya rẹ nitori wipe emi ni ọkọ rẹ lai ati lailai.

IGESE.

EKO AKETE

EKO, SATURDAY, OCTOBER 20, 1928.

## LILỌ LỌYA ZIZER SI ỌDỌ ELEKO NI ỌYỌ, PA-NTI-WA?

Irohin kan gbilẹ losẹ yi nipa lilọ ti a gbọ pe Ọgbẹni Lọya Zizer lo si ọdọ Eleko ni ode Ọyọ, a kọkọ ṣebi agbọsọ ni, ṣugbọn nikẹhin ni a wa ri gedegbe pe lotọ ni ọrọ na. Ohun ti a gbọ pe o lọ ṣe lọhun ni pe ki *Prince* Eşugbayi Eleko fun on ni aşẹ ki on Lọya le ma ba işẹ Ẹjọ Eleko na lọ a si tun gbọ pe awọn sanmari bi ọkan tabi meji ba lọ pẹlu. Ti o ba jẹ pe otitọ ni ohun ti a gbọ yi a rope eyiyi bayi jẹ ọna ẹburubu tabi ọna odi fun ẹnikẹni lati gbọ papa fun Lọya lati gba: a ṣebi Ọgbẹni Macaulay ti o jẹ Oguna gbongbo ẹniti o nwe ewe ẹjọ yi şi wa lori ilẹ gidipa a ṣebi gbigbe ẹjọ tamutamu yi fun Lọya Zizer ni akọkọ ko ṣẹhin Ọgbẹni Macaulay ẹniti o jẹ pe on ni ẹni pataki ti o mọ ayinike ayinipada gbogbo ẹjọ na lati oke de'lẹ. Nigbati Ọgbẹni Zizer si ni gbũngbũn gbun kan si Ọgbẹni Macaulay ni ijelo eyiti awọn agbagba dasi lati ṣe atunṣe rẹ ṣugbọn ti o di ẹti lilọ ti a gbọ pe Lọya na lọ si ọdọ Eleko fun biba ẹjọ Eleko yi kanna ma lọ ko ni şai jẹ iyanu fun ẹnikẹni nitoripe ni asiko kan ni Iwe-Irohin *Daily News* fi ẹkan sọ pe Ọgbẹni Ọlọla Eric O. Moore ati Lọya J. Kuşika Roberts ni awọn Lọya mejeji ti Eleko jẹ ọhẹn si lati ma ba ẹjọ on bọ ni Kotu ganran ati pe awọn ọmọ Ọba Dosunmu ti kọwe si Ọgbẹni Zizer ki o mu ọwọ kuro ni ẹjọ na ni riro: nigbana si ni ilẹ ti pa ewura da ti ẹnikọkan ko si tun gbọ pã tabi mu mọ? Şugbọn awa mọ pe ọna odi bayi ko le ba ẹnikẹni nije nitoripe a gbọ pe Ọgbẹni Lọya Roberts ati Ọgbẹni Braimah Igbo dakan lọ si ọdọ Eleko ni Ọyọ lati lọ ṣe abere ẹhin wiwa ti Ọgbẹni Lọya Zizer wa si ọdọ rẹ.

Loju wa ohun ti o şẹlẹ yi ku diẹ ki o to a ko le sọ pe Ologbo rajo ki'le di ile ekute tabi ki ẹnikan sọpe on le ta felefele si idi ẹjọ yi lalai jẹ pe ẹnikẹni fi işẹ rẹ na ran oluwarẹ.

Ọna alumọkọrọyi bayi ni o jẹ ọna ti ẹnikẹni ti o ba gba fi le da họwu họwu silẹ. A si tanma pe ẹni wa na ani Eleko ki yio gbọjẹgẹ lati fi ẹhin Macaulay dagun nipa titọwọbọ "iwe aramu" kọkan fun ẹnikẹni tabi fun Lọya ki Lọya fun biba ẹjọ rẹ bọ, afi awọn Lọya ti a ti yan fun ẹjọ na.

Ọgbẹni Macaulay ni o sọrọ Ọgbẹni Lọya Zizer pe o mọ ẹjọ şe daradara fun awọn ọmọ Ọba Dosunmu ki o to di pe nwọn gba ni Lọya fun ẹjọ Eleko ẹgbọn wọn na, ki lo ha si ti şe ti Ọgbẹni Lọya Zizer ko bẹrẹ lọdọ awọn agbalagba bi *Chief* Oluwa, Braimah Igbo ati awọn jakanjakan miran pe ki nwọn ba on rin ki on le pari ẹjọ Eleko ti a ti gba fun on ri ni akọkọbẹrẹ rẹ ki o to lọ si ilu Ọba; o daju pe bi Lọya na ba şe irufẹ eyi ni, ẹnikẹni ko ni sọpe ọna alumọkọrọyi ni o gba, alaişe eyiyi mu ki lilọ rẹ si Ọyọ ti oju su ni patapata, lilọ ti awọn Ọgbẹni meji si lọ sọdọ Eleko lati lọ şe abere ẹhin jẹ ohun ti o tọ gidigidi bibẹkọ, ọrọ na le bi IGE o si le bi ADUBI nitori awa ko gbe oju fifo le adie eyini nipe a ko rope Lọva Zizer le tun ba irufẹ ọrọ ẹjọ Eleko na lọ si Ọyọ lalai jẹ pe atunşe ti wa larin on pẹlu orisun ibiti ẹjọ na ti şẹ ki o to wa tẹ lọwọ ni şişe.

Ibi a gbe ti gùn ni a gbe ti nrọ.

---

## ỌLỌLA MOORE ATI AKISANYA.

### LATI ỌWỌ KEKERE-AWO.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete.*

Mo bẹrẹ f'oji,

*( Democratic Party's meeting September 22, 1928.)*

ỌLỌLA MOORE ALAGA :—Ọkunrin ti o sọrọ yi (Ọgbẹni Akisanya) nko ni ọro pataki lati fi ni esi nitoripe o ta mi lọfa ni mo si ni lati japoro, şugbọn nigbati o mọ wipe on duro gẹgẹbi Olopa-inu awọn, gbogbo ohun ti a nşe eyiti o ba yingin ninu rẹ kiloşe ti ko nwa si ọdọ mi lati ma fi idi bi nkan

na ti nlọ si han, eyiti ko ba ye ki nsi fi oye rẹ han an, nipa bayi ko ṣe to.

Ṣugbọn lori ohun gbogbo ti o sọ si mi lara, nko le sọ wipe bẹni gbogbo rẹ ri, omiran mbẹ nibẹ ti ko ri daradara, ti o ba di ni ọjọ omiran ti o ba ri ohun kan ti o yingin loju rẹ, ki o ma gbiyanju lati ma wa ii mi, ṣugbọn ọfa lo ta mi nipa ọrọ rẹ.

JONES, MOORE ATI DOHERTY.

A kole ṣe alai ba ẹnyin mẹtẹta yi sọrọ lori fun ibo titun ti ilu di fun nyin ati iṣẹ titun ti ilu gbe le nyin lọwọ, ti enia ba wọ ẹwu titun, ṣokoto titun, fila titun ti o ṣe ọṣọ lọ si ode, oluwarẹ ni lati jọ enia loju daradara bikoṣe awọn ọta oluwarẹ lo ma minu si oluwarẹ wipe hun......u kilo wọ, eke ni ori papa ko ri iru rẹ wọ ri, ki iyẹn ma ye gbogbo wa, amo n'sisiyi ọrọ awọn mẹtẹta yi jẹ ọrọ ti o sọ wipe omi titun de ẹja titun ma wẹ.

A ko ni aniyan lati sọ ohunkohun nipa Jones ati Moore, ọrọ awọn meji yẹn dabi orin kan ti o 'lọ bayi pe :—

"Ṣe 're, ṣe 're
Ṣe 're, ṣe 're
Ajiborisa ṣe 're,"

Orin yi ni a kọ fun Dokita Caulcrick nigbati ilu fi yan an si Igbimọ na ni ọdun 1925 nigbati ilu fẹ fi mu Kọlriki na, o pọ ninu awọn enia ti o ṣe kọdọyi ọkan si i wipe Kọlriki kẹ ni nwọn tun ma mu dipo Ṣingulu ninu gbogbo ogidileje enia ti o mbẹ ni ilẹ bayi, ti nwọn si ti ke u daradara nipa bi enia ti nṣe ilu si, ni ero awọn ẹlomiran ohun ti Ọgbẹni Makọli ba ti ni ki nwọn ṣe tulasi ni nwọn ma ṣe, o si wa ninu awọn ẹniti nwọn jumọ nse ẹgbẹ pọ ti nwọn tun mba wọn sọ bẹ lodẹ ni igbẹhin, iyẹn bi nwọn ba ti fete lẹkan lati ri ohun ti nwọn nwa ninu ẹgbẹ na.

O ni iye anfani ti Dokita Caulcrick ṣe fun ilu ti o yan si ibẹ niwọn igba ti o mbẹ ninu Igbimọ na, ti o tun padi nkun ọpọlọpọ enia ti o ti nṣe kọdọyi ọkan ri loju, iyẹn ni nwọn fi ma nsọ ọ lọrọ pe ohun ti Oluwa yio ṣe ko fihan ẹnikan, lori ohun gbogbo ti a o ba ṣe ki a ṣa fi otitọ inu pilẹ rẹ lo dara ninu yẹn ni awọn Maleka nṣe to! si!

A mọ wipe Ọlọla Jones ati Ọlọla Moore ki iṣe alejo ilu mọ ninu Igbimọ-Aṣofin, fun kini oju wọn ti da ṣaka nibẹ, nwọn si ti ri yẹkinni bi a ti ṣe nṣe ọran ilu ti o fi ndara, ani bi a tiṣe ba Ijọba sọrọ ni itubi inubi gẹgẹbi ọmọ tile ba baba rẹ sọrọ ti o ba nfẹ gba nkan lọwọ rẹ.

Ṣugbọn ọmọde ni Ọlọla Lọya Doherty jẹ ni ẹgbe wọn nitori ko de Igbimọ-Aṣofin ri pe on mba wọn ṣe ilu, debi ti yio fi mọ bi ẹṣin lo nṣiwaju kẹkẹ bi kẹkẹ lo nṣwaju ẹṣin, a ko sọ ti Igbimọ Munisiba o, nitori baba agba ni a le pe e nibẹ.

Gẹgẹbi a si tiṣe sọ wipe koi ti ni oye Igbimọ-Aṣofin, a ro wipe niṣe ti o ti de Munisiba yi yio ma mọ ta-ta-ta diẹ ko ya ni pọ ni, ṣugbọn iwọ jẹki nwọn lọ si Igbimọ na na ki a ki a to mọ irufẹ itu wo ni o le pa, iba ọrọ ti o yẹ ti a le ba a sọ di ọsẹ to mbọ lagbara Baba.

Ohun pataki ti a fẹ tẹnumọ nipa ọran Ọlọla Lọya Moore ni wipe ki o mọ wipe omi titun de ẹja titun ni lati wẹ, bi o tilẹ nwẹ daradara fun ilu ri, sibẹsibẹ awọn ni ko to ni ti awọn, nitorina awọn bẹ ki o wẹ, lọtẹ yi fun gbogbo ọdun marun ti yio tun ru ẹru ilu gba ki gbogbo Aiye gbọ wipe o ru omi na gudu-gudu, ki nwọn si kan sara si debi wipe kosi tabi-tabi awọn tun ni lati mu u ṣa ni, ni ọjọ omiran ọjọ 're.

Kosi ohun meji ti nwọn fi nyin Ọlọla Dakita Jones fun gbogbo ọdun marun ti o ṣe ni Igbimọ na ti o si ṣiṣẹ ti o yanju ketekete fun ilu gẹgẹbi iṣẹ ti nwọn ran, bi nwọn ba ni o dọwọ Imale o, Imale a ni o dọwọ Allah,

Emi ni ti nyin nitotọ,
KEKERE-AWO.

---

## Olusakin's Column.

### £500 FOR MR. MACDONALD.

**Large Bequests to Members of Labour Leader's Family.**

Substantial bequests to Mr. Ramsay MacDonald's family were announced yesterday to be a feature of the Will of Miss Florence May Gladstone, of Ladbroke-grove, W., Miss Gladstone, who was 72 when she died last July, left estate in her own disposition worth £44,486, with net personalty £41,143. She left :—

£1,000 between the five children of her late sister Margaret Ethel, who was the wife of Mr. Ramsay MacDonald, and £300, to her brother-in-law, Mr. MacDonald himself.

There are other bequests to Charities, etc. The residue, representing the bulk of Miss Gladstone's property, is to be divided equally between her ten nephews and nieces, or their issue if deceased.—*The News of the World*, 23/9/28.

### TORNADO'S TOLL.

**Appalling Record of Lives Lost and Damage.**

*(From our own Correspondent.)*

New York Saturday.—Information now available reveals the staggering extent of the disaster

caused by the great hurricane, which originated in the Windward Islands, swept over the Caribbean Sea and Eastern Florida, and spent itself in the coastal region here. It is estimated that the storm was responsible for :—

2,700 deaths, and injury to several thousand people ;

850,000 being rendered homeless ; and

Between £30,000,000 and £40,000,000 worth of damage to property.

PortoRico, West Indies, was the district that suffered worst of all. One thousand of the inhabitants perished, 20,000 were rendered homeless, and the damage to property exceeded £20,000,000. Florida suffered next severely with over 1,200 dead, 15,000 homeless, and £10,000,000 estimated damage. Six hundred bodies, chiefly of negroes, have been buried by the National Guard of Florida State.—*News of the World.* 23/9/28.

### Resumption of Duty.

Mr. Joseph Oladunjoye Oshoba, 2nd Class Compositor, Railway Press, Ebute Metta, who has been spending his leave at Kano and Ebute Metta, resumed his duty, as from the 27th ultimo.

### On Leave.

Mr. Daniel Tanimowo Abraham, 1st Class Compositor, Railway Printing Office, Ebute Metta, is on one month's leave, as from the 8th October, 1928.

### Birth.

Mrs. Serah Ajayi, wife of Mr. E. J. Ajayi of the Town Council Office, was delivered of two female twin on Saturday, the 6th October, 1928.

It is reported that both children and mother are keeping good health. Ki Oluwa ko ba yin wo wọn.

### Mr. H. M.-M. Moore.

By the R.M.M.L. *Accra* which sailed this port yesterday Friday, the 19th October, 1928, Mr. Henry Monck-Mason Moore, B.A., (Cantab) was among the passengers on leave to England, preparatory to his taking up his new appointment at Kenya Colony as Colonial Secretary.

We understand after Mr. Moore's departure Mr. Donald Kingdon, M.A., L.L.B., K.C., Attorney General, will act as Acting Chief Secretary to the Government, temporarily.

We bid Mr. Moore "Good-bye" and wish him *Bon Voyage.*

### On Circuit.

Messrs. A. Alakija, Barrister-at-Law, S. B. Rhodes, Barrister-at-Law, and Montacute Thompson, M.A., B.C.L., L.L.B., (Hons. London) Barrister-at-Law, sailed by the *Appam* on Thursday, the 18th instant for Port Harcourt on Professional engagements.

**Before His Honour Mervyn Lawrence Ag. Judge, Western.**

Monday, 22nd October, 1928.

### MOTION.

**In re an order under the hand of the Officer Administering the Government dated 6th August, 1925 etc.**

The above motion refers to Writ of Haebeas Corpus in re Prince Eşugbayi Eleko's case.

Who is going to conduct it ?

That is the question !

OLUŞAKIN.

### PRINCE ESHUGBAYI ELEKO SỌ IWE AṢẸ TI A SỌ PE LỌYA ZIZER JẸ KI O FỌWỌ SI DI OKU.

Ọyọ

15th October 1928.

Ọgbẹni J. C. Zizer, Lọya,

74 Opopo nla,

Eko.

Ọgbẹni Ọwọn

Mo fi iwe yi so fun ọ pe mo pa Aṣẹ ti mo fi fun ọ lati jẹ Lọya mi nipa ọran ẹjọ mi li oku lati oni lọ ki o yo ọwọ kuro ninu ọran mi ki o ma si ṣe Lọya mi mọ nipa ẹjọ mi ibã ṣe eyi ti o mbẹ ni Kotu Ganran ni o, tabi omiran ti o le ma rọdẹdẹ ni Kotu.

Emi ni tirẹ lailẹtan,

Ami

ESHUGBAYI ELEKO x

Rẹ

*Akọwe ali awọn Ẹlẹri*

Sanni Balogun,
OJo Sanni
Liamidi
Ọkan
Akọwe Amimu

*(Ẹda totọ lati ara leller papa).*

## IWE TI ELEKO KỌ SI AWỌN ẸBI RẸ.

Ọyọ 15th October 1928.

Si gbogbo ẹnyin Ọmọ-Ọba lọkọnrin ati lobinrin,

Ni ọjọ kọkanla oṣu October ti a wa yi ninu ọdun yi, mo ri Ọgbẹni J. C. Zixer *Lawyer* o wa si ọdọ mi pẹlu Ọgbẹni Akinọla Dawodu gbedegbyọ rẹ ati Adekọla akọwe rẹ.

Ohun ti o kọkọ fi ṣe ọrọ ni kiki ti o ki mi, o si sọ pe bi emi ko mọ on mọ, lẹhin eyi o fihan mi pe on ni Loya mi likoko.

O bere Lawani omọ mi ẹniti o ti wa ni Eko fun ọsẹ meji ti o si ti pada wa, o ba Lawani wipe ko mu ogiri si ọrọ Baba rẹ, o tun sọ wipe on gbọ pe mo ti gba awọn ẹjọ mi kuro lọwọ on, o ni emi iba ti pada wa sile ni ọjọ ti o ti pẹ, o ni ṣugbọn nigbati mo ti gba ẹjọ mi kuro lọwọ on nkọ.

O ni Ọgbẹni Macaulay kan ntan emi pẹlu awọn alatilẹhin mi jẹ sa ni, ti o si ngbọn owo danu lasan.

O ni ti emi ba le fi ọwọ si awọn iwe ti on mu wa, on yio sa ipa on gidigidi lati ba mu mi pada wa sile.

Ohun ti mo gbọ pataki ninu ọrọ rẹ ni yi ki nto fi ọwọ si awọn iwe rẹ, ẹnikẹni ko ka awọn iwe ti mo fi ọwọ si na fun mi, Ọyọ kọ ni a gbe ti kọ awọn iwe na nitoripe lati Eko ni a gbe ti fi ẹrọ ti nkọ 'we kọ wọn, o si ba mi pẹlu awon enia ti orukọ wọn wa ninu iwe ti mo fi pa Aṣẹ ti mo fifun loku emi ko ranṣẹ pe Ọgbẹni Zizer bẹni emi ko kọwe si lẹkan ri nigbatii mo ti kuro ni Eko. Ero mi ni pe o ti ri awọn Ẹbi mi awọn Ọmọ-Ọba lọkọnrin lobinrin Awọn Igbimọ ilu ati awọn Ijoye mi nipa ohun ti o wa ba mi sọ yi. Emi ko mọ pe o kan wa si bi lati wa tan mi jẹ ni, lati fi ọwọ si iwe rẹ, ọmọ mi fẹ ka iwe na ṣugbọn Ọgbẹni Zizer kọ fun un, ji gbogbo rẹ lọ mo ti kọwe lati pa Aṣẹ ti mo fifun na loku.

Emi ni tirẹ nitotọ,

Ami<br>
ESHUGBAYI ELEKO x<br>
Rẹ

*Lagos Daily News, 18/1928.*

---

## LAGOS STREET, EBUTE-METTA.

A ki gbogbo awọn ara adugbo yi ku aisun igbakugba ṣiṣe nipa awọn ole, awọn ole na si pọ ani dugbo yi to bẹ ti nwọn ko nfun wọn ni aye a ti ma sun fa loru ; gẹgẹbi ọrọ ti o sọ wipe "ṣiṣẹ ọsan simi loru," njẹ nipa awọn ole wọnyi awọn ara adugbo yi ha ni oju orun tabi isimi ?

Awọn ole na nma bẹrẹ si yonu lati nkan bi agogo meji titi de mẹrin-abọ. Idi ti ọle fi pọ be ni adugbo yi ko ye ni si arara, boya nitori alaisi ina manamana *eletriç* ni ko ye ni si.

Nitori na a bẹ awọn Onilu (olori Ọpa-Ọba) lati tunbọ ba ni fi awọn ọpa Ọba ṣọ adugbo yi ati lati boju to, nitori ti nwọn ba le ni ibalẹ ọkan ati anfani—a bẹ nyin o.

---


# NOTICE.

IN THE MATTER OF THE ESTATE OF

## AKINWUNMI AJOSE-ADEOGUN,

(DECEASED).

*Pursuant to the Statute 22nd and 23rd Victoria Chapter 35, intituled "An Act to further amend the Law of Property and to relieve Trustees"*

Notice is hereby given that all creditors or other persons having claims or demands upon or against the estate of Akinwunmi Ajose-Adeogun late 25, Agbojo Street, Idoluwo, Lagos, Nigeria, who died on the 9th day of July, 1919, intestate, and Letters of Administration of whose personal property were on the 9th day of August, 1928, granted by the Supreme Court of Nigeria to Akinola Ajose-Adeogun of 9, Ajose Court, Lagos aforesaid, are hereby required to send particulars of their debts, claims and demands in writing to me the undersigned on or about the 30th day of November, 1928, after which day the Administrator will proceed to pay and distribute the assets of the said estate among the parties entitled thereto, having regard only to the claims of which he shall then have had notice and that he will not be liable for the assets or any part thereof, so distributed to any person or persons of whose debts, claim and demand he shall not then have had notice.

And all persons sndebted to the said estate required or holding any effects of the said deceased are hereby to make immediate settlement or deliver the same to me.

Dated at Lagos this 15th day of October, 1228.

AKINOLA AJOSE-ADEOGUN.<br>
*Administrator.*

## INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi" jẹ ojulowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ṣẹṣẹ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Ṣango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Oriṣi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maṣe gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

---

JUST ARRIVED.

**WASU**

journal of the West African Students' Union of Great Britain.

**1/- per copy.**

**Obtainable at the office of :—**

"TIKA-TORE" PRESS,

Broad Street, Lagos.

## IROHIN ẸNUGU.

Oyẹ ohun to ya ni lẹnu lati ri wipe awọn oni gbagbọ meji iera wọn ninu ṣọṣi church—bẹni ẹlọ ki le ẹfọ lamo. Lati bi iwọn ọpọlọpọ ọdun sẹhin ni awọn Ibo ati awọn Ilesha ti ju mọ nlọ si Ile ẹsin kanna. Ṣugbọn ninu ọdun 1928 yi. Awọn Ibo sọ fun awọn ara Ilesha pe ti wọn ko ra le gbaredee, Marry ki wọn ma wa si Ṣọṣi (Church) wọn mọ wọn si le won jade, bẹni won jiјọ nda owo sinu Ile-Ọlọrun Church yi ni.

Njẹ ẹnyin ara Onigbagbọ ẹ lawa loye, kinni yẹ tabi totọ ki awọn ara Ilesha ki o ṣe nipa owo wọn to wa nbẹ?

Lẹhin gbogbo iwọnyi awọn ara Ilesha na papa ti gbaradi lati kọ ṣọṣi Church ti wọn lotọ. Adura mi si wọn ni pe Ọlọrun Olodumare ko ran wọn lọwọ ninu ero wọn Amin. Ninu oṣu July won tẹ waya (Telegram) si olori Alufa U. N. A. Church ni Ebute-Mẹta lati le fun wọn ni Alufa lati wa fi Ipilẹ Ṣọṣi (Church) lelẹ fun wọn tabi ko wa ba awọn ṣi Ṣọṣi Church ti awọn ngbero lati kọ. Ka ma fa ọrọ na gun titi mọ, ni 8th July, 1928. Sunday wọn pe Chief Sannie Animashanu ati awọn ẹmẹwa rẹ lati le wa ba wọn fi opo (Pole) Ṣọṣi Church bọlẹ. Church Sannie na si ṣe bẹ pẹlu gbolohun adura ai:—

Ibukun ati abusi Oluwa Ọlọrun ko wa lori ile Ọlọrun ti awọn ara Ilesha gbero lati kọ yi. O si mu opo (pole) na dani. O si ṣi fila rẹ, o si ri mọlẹ. Oluwa ko ran awọn ara Ilesha lọwọ, Amin.

---

Anu ṣe wa lati gbọ pe Ogbẹni Alagba wa lọ si ile ipamọ fun oṣu mẹfa. Awọn abinu ẹni ṣe, ṣugbọn wọn ko le pa kadara da. Ṣugbọn ki wọn mọ daju pe Olodumare nikan lo mọ ẹhin ọla.

A ki gbogbo ẹgbẹ Dẹmọ wọn ku ajalu na. Oluwa ko mu pada wa bawa pẹlu alafia Amin.

---


## KERE O!

Mr. C. B. SHODIYA, *Produce Buyer*, ti No. 132, nitosi Niger Company, Ebute Ero, ni ọpọlọpọ Tapo (Tapaulin) siye 15 x 15 fun hihaya, bi o fẹ ṣe ariya ti Iyawo lọ sibẹ, bi o fẹ ṣe Wolimọ lọ sibẹ, bi o fẹ ṣe ariya nipa ti oku lo sibẹ, o wa fun ẹnikẹni ọpọku-oyọku ni owo hihaya rẹ.

9d. ẹgbẹdogun fun Tapo kan lojumọ.

C. B. SHODIYA,
*Produce Buyer*,
132, Ebute Ero,
Marina, Lagos.

## *Use Yaro for your baby!*

All experienced mothers give testimony in praise of "Yaro" as an indispensable 'Preservative' for 'Babies.' Yaro has no equal in suppressing those complaints which make infants feel uneasy, especially during their critical teething period. Trust Yaro for all infants' complaints and use it for your baby. Price per bottle 3/3d & 2/3d

## *Increased health for 3/- only.*

"Life Tonic Tablet" imparts tone and vigour to the body, renews every atom of the flesh, prevents brain fatigue and brings indescribable comfort to all mental workers. Price 3/- per bottle.

## *A chance for female sufferers.*

Wireless Female Pills, the latest Scientific Discovery, have answered divers cases of functional complaints of disorders peculiar to women. These Pills serve as an effective fertiliser against barreness. Give "Wireless Female Pills" a trial and prove its reliability.

Our Anti-Plague Disinfectant Fluid kills dangerous flies, bugs. cockroaches, etc., etc. 1/- and 1/6d per bottle.

### *Anti-Gon Pills.*

Get rid of veneareal diseases before they get rid of you by using Anti-Gon Pills--a reliable antisceptic against Gonorhea. 3/- per bottle.

WE ALSO STOCK:—

Glaxo (large and small sizes)
Vitafer—Brain Tonic
Walk Easy Anti-Rheumatic Salt 3/6 & 2/-
Pile Pills 1/6
Vibrona Wine 7/6
Lactogen
Kalzana
Effective Pile Remedy 7/6
Back and Kidney Pills 2/-
Zotal 1/6 & 2/6

*Obtainable at:—*

# IYIN OLUWA MEDICINE STORES

*Head Office:*—88, Broad Street, Lagos,
*Branches:*—6, Martins Street,
41, Alli Street, Faji Market,
109, Griffith Street, Ebute Metta.

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH.

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.,
*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road,* ***Lagos.***
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

---

ARẸMỌ FUN ỌKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o njẹ pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo arun ti ki jẹ ki ọkunrin ṣe abiamọ.

*N.B.*—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loṣoṣu—Iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.

*Postage 2/6 extra.*

---

## hite's Golden Female Tonic

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.

41, Offin Road, Lagos.

*N.B:—Not obtainable elsewhere.*

---

GBOGBONIṢE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ, ati oriṣiriṣi arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.

**Postage 2/6 extra.**

---

WHITE'S

## WON DRFUL BRAIN TONIC

This medicine stimulates and rebuilds the [illegible] in such a way, that the regular user is able to [illegible] many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by **SAMUEL VICTOR WHITE, Esq.**

41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.

N.B.—*Scholars should not be without it.*

---

EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe ṣiṣẹ ati gbogbo awọn ti o [illegible] lati lọ fun idanwo.

*Iba ṣe ọmọde tabi agbalagba.*

---

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy or Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Ṣick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ, *Chemist,*

The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos

"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.

*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

---

EGBOGI ILN Ẹ JẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oṣu rẹ mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aṣẹ Ewurẹ pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to :—

MR. MOSES O. COKER,

Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specifie acts like Magic : has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

*Cable Address* :—" WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIRẸMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

## Indents House.

Import of General Lines

Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

## TO LET.

One Splendid Pleasure Car

No. L2754.

**Always at everybody's service at Tinubu Square.**

For Terms, Apply to —

A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

## ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

### Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

—— : o : ——

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmini ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọju si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorişirişi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi aba, awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fun ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.

Printed at "Tika-Tore" Printing Press, 20, Market Street, Lagos, and Published by Adeoye Deniga at 24, Williams Street, Lagos, Writer and Lecturer.